The Hon. ... Chief Secretary
To ... Sept ...


# EKO AKETE.

IWE IROHIN OSOSE.

VOL I. No. 17. SATURDAY, NOVEMBER 4, 1922. THREEPENCE.

*Editor:*—ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Odun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹta | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.


## GBOHUN-GBOHUN.

### OGUN BURU ILU KÒ DUN.

Ni Ile-ẹjọ awọn Ọlọpa ni *Monday* ọsẹ yi, *(30th October, 1922,)* Adajọ da ẹbi fun awọn enia wọnyi, nipa ẹsun ti awọn AHMADIA fi sun wọn: eyiti a rohin rẹ ninu iwe yi ni ọsẹ diẹ sẹhin.

Ẹsun Ekinni:—Nwọn pejọ lati ṣe enia ni jamba.

„ Ekeji:—Nwọn yọ awọn ti o nsin l' ẹnu.

1. WUSAMU CAREW. 2. SUNMOLA MUSA.

Ẹwọn oṣu kọkan, Iṣẹ-Aṣegan, *(Hard Labour)* fun Ẹsun Ekinni: ogun ṣile ni sisan s' apo Ọba ẹni-kọkan fun Ẹsun Keji.

4. RAJI. 5. ALAJI BELO.

Ẹwọn oṣu kọkan, Iṣẹ-Aṣegan *(Hard Labour)* fun Ẹsun Kinni: ogun ṣile ni sisan s' apo Ọba fun Ẹsun Keji.

6. ADAMU ANIMASAWUN. 7. BELO ARO-WASI.

Ẹwọn oṣu mẹta-mẹta, Iṣẹ-Aṣegan (*Hard Labour*) fun Ẹsun Kinni: ogoji ṣile ni sisan s' apo Ọba fun Ẹsun Keji.

9. JIMO ANIMASAWUN. 10. ASHIRU.

Ẹwọn ijọ merinla, Iṣẹ-Aṣegan *(Hard Labour)* fun Ẹsun Kinni: Nwọn ko jẹbi Ẹsun Keji

3. JINADU CAREW. 8. AMODU MUSE.

Adajọ da awọn yi silẹ, wipe nwọn ko jẹbi.

Akinlade ... Editor
Akin Adesigbin

Oruko awọn Lọya ti awọn Ahmadia gba, ti nwọn tako wọn ni eyi :—Awọn Ọgbẹni Kitoyi Ajasa, E. J. Alex Taylor ati Adeyẹmọ Alakija. Orukọ Lọya ti awọn ti a fisun yi gba ni Montacute Thompson.

A gbọ pe nwọn tun fẹ gbe Ẹjọ na dide ni Ganran. (*Appeal*)

## KABỌ, BABA.

Awọn Ijọ Alalukurani ati Amadia lọ ki Ọgagun H. C. Moorhouse, Igba-kẹta Ọba "Kabọ" ni ọjọ *Tuesday* (Atalata) ọsẹ yi.

## ANỌBI FA LALA, FA A LALA, LA, LA LA LA.

A ri i ka ninu Iwe-irohin ti Ilu-Ọba *West Africa*, ti ọjọ keje oṣu ti o lọ, pe diẹ ninu awọn enia wa ti o jẹ Musulumi ti nwọn lọ ṣe Āji ni Mecca ninu oṣu *April* ọdun ni, nba ọkọ *Appam* bọ wa 'le: orukọ wọn na ni eyi :—Alaji Lawal, B. Martins ati aya rẹ Haja Barikisu: awọn Alaji Mọmọ Karafi Ajala, Saka Jinadu, Alufa Bakare, J. C. Bakrin, Ọtun, Yusuf B. Pedro, Rufai, B. Ajala Salimọnu, O. Danmọle, Shittu J. Alaka ati Muhamad Tijani.

## ỌBA ALAṢẸ EKEJI ORIṢA.

Gomina yẹ lilọ rẹ si Cameroons nitoripe Ọkọ "*Elmina*" ti iba mu lọ pẹ lati de ibi lati Ilu-oyinbo.

## KINIUN ONIBUDO NLỌ S' AJO.

O ta si wa leti fẹnrẹn pe Sonigbe ti a ṣeṣẹ fi jẹ Ọba Ẹgun l' Ajaṣẹ nranṣẹ ẹyẹ si Ọgbẹni Herbert Macaulay pe ki o wa ki on fun ōre ti o ti ṣe on, ati "asọtẹlẹ" ti o ti sọ pe on (Sonigbe) yio rọ'po Tofa nijọkan: a sọ pe ọrọ yi si ṣe l' ọdun ni, lati iwọn ọdun mẹrindilogun ti a gbọ pe Ọgbẹni Macaulay ti sọrọ na fun u.

"Olõre kã ku, õre, olõre kã run, õre t' owo t' ọmọ i-ja-wa !!! i-ja-wa !!!!

## AJINDE ARA AMA JẸ WA.

Ni Ipade ti a ṣe ni Ile-Iranti Afari Ogu ni ọjọ *Wednesday* ọsẹ ti o kọja, a fi Ọjọ Ilera si ọjọ *29* oṣu yi titi fi di ọjọ 2 oṣu *December* ti o mbọ.

## EṢUGBAYI ỌMỌ ALADE.

"Bi iku ile ko pani, ti ode ko le pa ni"

Awọn ọrọ aida ati ifiniṣẹsin ti mo ri ka ninu iwe irohin kan ti a npe ni "*African Messenger*" ti awọn ọjọ 5 ati 12 oṣu yi nipa ọrọ Eleko ni o ka mi lara lati fọhun sinu iwe wa yi ni ọsẹ yi. Nigbati mo fi oye wo awọn ọrọ ti iwe na sọ nipa yẹyẹ ati ṣiṣata ti ẹniti o kọ iwe na fi ko wọn; mo mi ori mi ng ko si mọ igbati owe yi bọ lati ẹnu mi pe "Bi iku ile ko pa ni, ti o de ko le pa ni" awọn baba wa ni nwọn ma nsọ pe 'Okete ni ẹniti o pa on, ko to ẹniti o gbe on ṣan 'lẹ." lotọ awa enia dudu ni ota ara wa, ko si ibi kan ti awọn oyinbo nṣe si wa.

Lati igbati awọn ijọba ti da Eleko duro, nigbawo ni a gbọ tabi ti a ri ka ninu iwe wọn ti wọn bẹrẹ si fi ṣe yẹyẹ tabi ki wọn ma ṣọninu? Mo fẹ ki ọgbẹni ti o kọ awọn ọrọ yẹyẹ wọnyi gboju soke ko si wo orun wipe idajọ kan tun mbẹ lẹhin ti aiye. Ọgbẹni ti o kọ iwe na fi ẹnu kan iwe Irohin kan ni ilu oyinbo ti a npe ni "*The African World*" o si tumo awọn ọrọ ti iwe Irohin na sọ nipa Eleko gẹgẹ bi o ti tọ ni oju ara rẹ, mo fẹ ki ọgbẹni na mọ pe awọn oyinbo ti wọn nkọ iwe yi, nwọn ko mba wa gbe ilẹ yi, nwọn kosi mọ. iṣoro pupọ ti o mbẹ fun ọba wa, ohun ti a ba si kọ sọwọ si wọn ni nwọn ma ntẹle.

Iwe-irohin kan ti a npe ni "*West Africa*" sọ ni asiko ti ọrọ Eleko yi bẹrẹ wipe awọn ko ri ẹṣẹ paraku kan ti Eleko ṣẹ ti a ko le fi dariji i. Ọgbẹni na fi ẹnu kan nipa Iwe-ẹbẹ, o si sọ ọ ni ọrọ yẹyẹ ati ṣiṣata bayi pe :—"Maṣe *Petition*, maṣe *Petition*," bẹni, iran ẹniti o ba ti mọ pe on ṣẹ ni o ni lati bẹbẹ, yala a o gba ẹbẹ na ni o tabi a kio gba ni o, oluwarẹ ni lati jirẹbẹ. Ọgbẹni na si tun sọ bayi pe, "Ṣugbọn ki a tilẹ gba pe Ijọba gba Iwe-ẹbẹ na, pe nwọn si dariji Eleko, kinni eyini? ṣe pọun mẹdọgbọn oṣoṣu? mo fẹ lati da Ọgbẹni na lohun pe bẹni, ko ju pọun mẹdọgbọn oṣoṣu lọ; owo ti Ọga Akọwe ngba nigbati Eleko ba ranti pe Ọba (*King*) ni Ilu Oyinbo ngba owo oṣu, iyekiye ti o le wun ki o jẹ ti o si jẹpe on ni alaṣẹ gbogbo awọn ti wọn nṣe owo yi, o yẹ ki Eleko dupẹ lọwọ Ọlọrun pẹlu itẹlọrun, iyekiye ti a ba fi ja lọwọ loṣoṣu, o si tọ ki

a bẹbẹ fun iwọn diẹ na, bi ko tilẹ to bẹ; a njẹ ekuru ko tan, a si tu ngbọn ọwọ rẹ sawo—ẹ tun gbọ ohun ti Ọgbẹni na tun wi—"Ipa wo ni Olori Ile Dosumu le sa ni ilẹ yi loni? Ọlọpa onişoko penpe ni ipa ju u lọ" mo ka eyi si ọrọ ọmọde ti nko ri esi ti mo le fi si ju họ lọ!

Bi Ọgbẹni na ti jẹ Egun nla ti nfọhun bi enia ko sa le fi ọwọ sọ aiya pe on le mọ ohun ti Ọlọrun le şe ni ọla.

Gomina Clifford—jẹ ẹniti inu gbogbo wa dun si nigbati a gbọ pe wọn yan bi Gomina si ilẹ wa, gbogbo wa si nyọ pe asiko rẹ yio dara fun wa gẹgẹ bi asiko rẹ ti dara fun awọn ara ilu Gold Coast, şugbọn ohun ẹdun wa ni o jẹ pupọ nigbati ọrọ Eleko yi ti bẹrẹ o si mu ni ro pe awọn ara ilu Gold Coast jẹ awọn ẹda ọlọrọ-kan, şugbọn nigbati o de ọdọ awa ọlọrọ meji o mu ki ọrọ na fẹ su ni, o si da gbogbo ẹbi na sori Eleko, agba lo sa njiya ọmọde, şugbọn ohun ti o ma dara pupọ ni bi Gomina na ba le fi iyedenu, ko si ro wo pe Eleko ko le kawe, ko le kọwe bẹni ko gbọ ede Gẹsi, bawo ha ni ainişinilọna kio şai wa larin on ati Eleko?

Bi a ba bojuwo ẹhin a o ri pe Eleko ti ba awọn Gomina kan lo awọn ẹnibi Egerton fun ọdun meje ti o fi wa ni arin wa a ko gbọ pe ede-aiyede bayi tabi ipaiya wa fun Eleko; bẹ na si ni ọkunrin jẹjẹ abiwa kikun, Gomina Lugard ẹniti o jẹ pe ati oyinbo ati enia dudu ni o mọ asiko rẹ lara, şugbọn a ko gbọ pe Eleko ri iru wahala ati aibalẹ-aiya bayi ni asiko tirẹ, eyi ni o mu awọn baba wa lati ma pa owe yi pe "enia buburu ni igba rere tirẹ," o da bi ẹnipe Gomina Lugard mọ pe ko si bi Eleko ti le mọ şe to ki awọn enia ma fi le şi i ni ọna nitori aimọwe rẹ, nitorina Gomina Lugard jọwọ rẹ si ipo rẹ ko si ba Eleko jijakadi kankan rara.

Eyi ni a fẹ ki Gomina Clifford mọ pe ẹşẹ Eleko jẹ ti gbogbo ilu ẹniti o ba si sọ pe on ko ni ọwọ ninu rẹ, njẹ oluwarẹ ki nşe ọmọ-ibilẹ, alawọşe ni oluwarẹ jẹ; ao si fẹ lati ma darukọ Gomin Clifford fun rere lẹhin igbati o ba pari işẹ rẹ ni ilu wa.

Ẹyin ti o nkọ iwe yẹyẹ ati şişata, ẹ lọ wa 'bi sinmi si, elukaluku-abi-tirẹ-lara, ka tilẹ wipe Ijọba ko gba ẹbẹ, o şoro k' a to fi Iran Aje'nia kan dipo Eleko, ati pe bi Ijọba ba tilẹ ni jagudapali ẹlomiran ni awọn fẹ, mo fe ki ẹ mọ pe ẹgba ti a fi na iyale o mbẹ ni aja fun iyawo; nitorina ẹ fi Eleko silẹ pẹlu Ijọba, ẹ ma şe şọ Eleko ninu mọ pẹlu Ijọba, nitori gbogbo aida nyin ti ẹ nsọ tabi ti ẹ nkọ ni awọn Ijọba nri ti nwọn si ngbọ ti o si wa ni ipamọ fun ọrọ ọmiran ati pe yẹyẹ, aini-ọrọ kan-lẹnu ni nwọn si nfi nyin şe.

Ẹ gbọ orin ti Bişi, ọkan ninu awọn gbajumọ akọrin wa kọ ni sa kan bayi pe:—

"A fi enia dudu fi şọ enia dudu
A fi enia dudu fi şọ enia dudu
Bi ẹ o ba ronu wo, ẹ ko ma şeun
Bi ẹ o ba ronu wo, ẹ ko ma seun."

AWỌLUJẸ.

---

## MATTERS IN TOWN

BY

PATRIARCH CAMPBELL.

---

As Alli Balogun, Lemomu Braimah, and others are bound over the peace and now Adam Animashaun, Belo Alaji, and others find themselves in jail over the Mohammedan religious controversy I think it is high time for the Mohammedans to know that every sane being in Lagos is disgusted and tired with the whole affair and our contention with the *Nigerian Pioneer* that the matter was more of a religions controversy than a political one is now clear to all.

The Mohammedans in Lagos ought by this time to show that they are amendable to reason, and they should be ashamed of themselves as it is known I was the very first person who tried to speak peace to the people in the Central Mosque but no go. The Government for seven years tried to speak peace but of no avail. The Magistrates and Judges endeavoured to temper justice with mercy so as to bring peace but no avail. His Honour the Lieutenant Governor Colonel Moorhouse and Major Walker tried at last and effected some reconciliation but it seems that some will still have their way Let the Mohammendans know everybody is tired with whole things perhaps except the Lawyers whose coffers will be filled when doing their honest duty by prosecuting and defending: but it is none of their fault they are only doing their legitimate work. My advice is let all the the Newspapers in town including the *Nigerian Poinceer* cease saying anything of the Mohammedan quarrel for the next six months and let the matters be left with the Magistrates and Police a few mouths or weeks in Grey s Inn to the disturbers of the peace who have not the commonsense to know that bye gones should be byegones will perhaps have the desired effect and this unnecessary Religious Controversy in which Prince Eleko through want of foresight has got himself involved under a political garb will perhaps under God's grace come to an end.

J. G. Campbell.

## *EKO AKETE.*

EKO, SATURDAY NOVEMBER, 4, 1922.

### DARAN-DARAN ẸIYẸ TI NMU'SAN

Ohun ti o ṣẹlẹ ni ãrọ *Monday* ọsẹ yi, *( 30/10/22 )* nipa ti awọn ara wa ti o jẹ Imale mẹjọ, ti Adajọ kekere, Ọgbẹni H. A. YOUNG gbe ju s' ẹwọn ni Ile-ẹjọ awọn Ọlọpa, ba ẹnikẹni lẹru: irufẹ agbako bayi li o yọ, nigbati awọn Ahmadia lọ ṣe Wasi lalẹ—gẹgẹbi aṣa wọn kakiri ilu—ni Ita Balogun ni ọjọ *Friday*, ọjọ kọkandilọgbọn oṣu *September* ti o kọja, nigbati awọn ọmọkọmọ kan bẹrẹ si i sọ wọn l' okò laiṣẹ lairo, tobẹ̃ ti o fi jẹ pe enia pupọ ni a ṣe leṣe ni iru ọna yi. O jẹ ohun ti o dun ni lọpọlọpọ, pe gẹgẹ bi a ti ng wipe a la'ju ni igboro ilẹ yi to, a tun nri awọn kan ọlọrun-lile ti o nyọ̀ ninu ki nwọn ma a di awọn ẹlomiran lọwọ ni ọna Isin wọn nigbati a ba nṣe Wãsi ni Opopo-Ode: dajudaju, irufẹ iwa jagidi-jagan ti awọn enia wọnyi hu ni alẹ ọjọ na,—bi o tilẹ jẹ pe ọmọ-lẹhin Anọbi MOMODU ni nwọn npe arawọn,—ni o ko ba ADAMU ANIMASAWUN, BELO AROWASI ati awọn mẹfa toku ti nwọn fi di ẸLEWON ỌSAN-GANGAN bayi!!! Nitõtọ, a gbọ pe awọn enia wọnyi kosi nibẹ, ṣugbọn nigbati a sọ ọ lọ, sọ ọ bọ, ni KOTU, Adajọ sọ pe on gbà pe lõtọ ni nwọn wa nibẹ: ohun ti o si tubọ mu Ẹjọ na le ni pe gbogbo wa li a mọ̀ pe nigbati Ijọ ti ILU ati ti LEMOMU ṣe ãwọ̀ laipẹ yi, ti o fi di ọran KOTU, tọtun-tosi wọn ni Adajọ kiwọ̀ fun ọdun kan, eyi ṣẹlẹ ni ọjọ karun oṣu *September* ti o kọja: ki a si tun wa gbọ pe ọkan tabi meji ninu awọn ti a ti fi Ofin de mọ'lẹ fun ọdun kan bayi ni a tun mu wa siwaju Kõtu kanna fun ẹsun miran ni ọjọ ti ko jina si arawọn, bawo ni igbẹhin nkan bẹ ti le ri o? Ẹ ko wa ri bi awọn Abi-ikọ-ọmọ ti le da si ẹlomiran ti ko m' ọ́wọ ti ko m' ẹsẹ lọrun bi? ki EDUMARE gba ni lọwọ Adunrunmọ. Iwa awọn ti o ṣe jamba si awọn Oni-isin bayi ko wọ̀, o si dun ni pe Ofin ko jẹ meji tabi mẹta ninu awọn ẹniti o sọ okò pãpã bẹ̃ ni 'ya fun ikilọ ijọmiran.

A tanmọ pe ọran yi yio kọ pupọ awọn ọmọ Imale l'ọgbọn lati mọ pe abẹ ãbo Ọba (*King*) ni gbogbo wa wà ni ilẹ yi, ati pe kosi ẹniti o le jẹ ọmọnikeji re ni 'ya ajẹgbe, lai jẹ pe Ofin mu irufẹ enia bẹ̃ kọ bi akukọ: kosi Ofin ti o ni ki onitirẹ k' o ma ṣe e, niwọn igbati irufẹ nkan bẹ̃ ko lodi si Ofin; Ọrọ Ọlọrun ko mu ija wa, ni a ti ngbọ ri lẹnu awọn Musulumi, ṣugbọn nigbati a ba gbagbe eyi, ti a ba si nyọ awọn Oni-Isin ni ọna miran lẹnu gẹgẹ bi eyiti o da "họwu-họwu" silẹ yi, iya ko ni ṣai jẹ irufẹ ẹnikẹni ti o ba lọwọ ninu nkan bẹ̃.

Ati Abọriṣa, ati Onigbagbọ, ati Imale, kosi ẹniti Ofin ko wà fun. A si ni ireti pe ohun ti o ṣẹlẹ yi yio mu olukuluku s' agbeje mọ 'di, yio si mu wa dẹkun ati ma a lọ jẹ oye "Fatolu, ọyọju-ọran."

Bi o ti wun ni ni a nṣe 'Male ẹni, o fi apa ẹlẹdẹ ṣan sãri!!!

---

### IROHIN OKE OKUN (ENGLAND)

LONDON 31. 10. 22.

Ninu waya (*Reuter's Telegrams*) ti o de ni ọjọ *Tuesday* ọsẹ yi, a ri ka pe Ọga awọn Gomina ti a ṣẹṣẹ yan ni *Duke of Devonshire*, Ọgbẹni WINSTON CHURCHILL ti fi ipo na silẹ nigbati "ina ru" ti a fẹ yan awọn Igbimọ titun *(New Parliament)* miran. Ọba *King* fi aṣẹ si i pe ki Igbimọ titun na pejọ ni ogunjọ oṣu yi.

Ọgbẹni JAMES FAULKNER ara Saro, gbe omidan Ada ṢOMEFUN, ọmọ Ọgbẹni ṢOMEFUN ti Agege, ni iyawo ni ibi ti a npe ni Streatham.

## KILOPO? 3.

LATI ỌWỌ, *EDITOR* EKO AKETE.
[ A ko gbọdọ da Iwe yi tẹ lai gba'ṣẹ.]

### SURU BABA IWA.

Nigba gbogbo ni a ma ngba enia niyanju pe ki o mu suru nigbati ọwọ oluwarẹ ko ba tẹ ohun ti o nleba ibaṣe iṣẹ ni, tabi nkan miran; ọrọ yi si jẹ ohun ti a fi ntu awọn miran to ba wa ninu ibanujẹ tabi ironu ninu, a si ni owe wa kan to wipe "ibinu ko da nkan, suru baba iwa:,' a ko le sọ iyo adanu ti awọn elomiran ti pa nipa pe boya nwọn ti fi "wadu-wadu ja 'da lori ikọ."

Nitotọ a mọ pe iyanju yi ṣoro lati tẹle nigbamiran to ba jẹ pe ara wa nwa papa lati se ohun kan: gidipa, a le sọ pe *Job* ti a npe ni "ọkọnrin ti o mu suru ju, ninu irora ati ninu ofo pupọ" fẹrẹ bọ 'hun nigbati idanwo desi nijọ-kini tobẹ ti o fi fi ọjọ-ibi rẹ re:* ṣugbọn sibẹsibẹ, a ri pe ki ṣe ohun to dara lati ma kanju nigba-gbogbo fun ohun ti a ba fẹ ko yọri: bẹ si ni a ko wi fun ẹnikẹni lati mu irufẹ suru omugọ enia kan ti o mọmọ kan lu 'do lai mọ ṣe "tabu" ti ko si kigbe fun iranwọ, to ka ọwọ bọ itan ninu omi to si nreti igbati ao wa yọ on ninu evu to wa, ! ! ! opo ati iko-aiya-soke lo nmu ẹlomiran gbẹ si iduro fun nkan ti a ko ba ṣe suru diẹ fun, Ẹlẹda wa Tikalarẹ nkọ wa ni iwa suru ninu gbogbo iṣẹ Rẹ lode aiye: ki sa nṣe ijọ ti a ba gbin igbado ni a nri ọmọ ẹ ya jẹ, ijọ ti a ba si bi ọmọ kọ ni o nrin; iwarapapa nje ki a sọ nkan nu nigbamiran. "Ohun ti a fẹsọ mu ki nbajẹ, ohun ti a fi agbara mu ni nni lara" njẹ, nitorina, Kilopo? *Job iii. 3—10.*

### IGIDA

Gbogbo wa la mọ pe nigbamiran ohun ti a ti nreti le jatilẹ loju wa: bọya owo-geregere ta ti na si ori nkan bẹ a di ofo. "Igida" si ni igbe wa nigbayi: ṣugbọn o yẹ ki a mọ pe "igba ko lọ bi orere" niwọn igbati a ba ti mọ eyi ibanujẹ ko ni ṣai-dinku, idamu ọkan pelu wahala ara ki nba ni ro rere:— Kilopo?

### IWA L' ẸWA.

Bawo lo ti dara to fun olukuluku wa lati mọ iyi iwa ọmọ-luwabi: ibaṣe l' ọkunrin, l' obinrin; pẹlupẹlu iwa rere jẹ ohun kan ti ki nṣai ni ere tirẹ; a ko sọ pe nitoripe ki a ba le ma ri ere gba lo yẹ ka ma hu wa rere; ṣugbọn o jẹ ohun kan ti o ni ogo tirẹ. Anfani ki lo wa lara ẹniti a npọṣe si orukọ rẹ nigbakugba ti a ba nda orukọ na? boya irufẹ ẹni bẹ ti jẹ 'jẹkujẹ ti o sọ iwa rẹ di abawọn; o yẹ ka ma ranti nigbakugba pe "Iwa l' ẹwa, ẹwa kan ko si nibikan."

### ỌRỌ ẸRIN!!

Ẹniti a bẹ lori ti nyin 'mu, eyiti yio tun ṣe ku!

Ki a rin, ki a pọ, yiyẹ ni i yẹni, ṣugbọn bi ti ẹlẹwọn ma kọ o!

Ẹniti o goke ki o fa ara rẹ lọwọ, ṣugbọn bi ti ori ọpẹ kọ ṣa!

Ẹniti aba la nbi, ṣugbọn bi ti Ọlọpa kọ, bi ti Akọda kọ, a jẹ pe o ku ohun ti yio tun bi!!

"Mo gbọ ti Iyawo, kuruna ni ko jẹ ng wa!!"

Ki a maṣe jale, ki a maṣe fẹwọ, bi ki a ri sisi (6d.) lọju ọna ki a ma he e ni bi o? Ewọ!!

Bi a nyan Eṣu lodi, o jọun pe ki nwọn fi ṣile kan rubọ sori rẹ ki a mọ ọ loju ni? Agbẹdọ!!

Ke! ki ng ba ọ ke, Adẹtẹ Ẹrunmu, ilu wo ni nwọn ti nyan akara, laitọwọ bọ epo? (Adẹtẹ fẹ yan akara elepo, akara ẹri, alakara gbowo tan, Adẹtẹ fẹ tọwọbọ inu awo akara! alakara figbe ta pe, ma tọwọbọ o, ma tọwọbọ o, ni Adẹtẹ dahun pe, ha ha!! tọwọbọpo ni mo fẹ ra kẹ! njẹ ke, ki a jọ ke. !!!)

OGUNLANA.

## OPEN LETTERS. No. 4.

TO THE RIGHT REV. BISHOP JONES, D.D
Bishop of Lagos.
Bishopscourt, The Marina, Lagos.

My Lord,

Please accept my congratulations on your episcopal pronouncement against "Colour Bar" in the Church under or having a leaning on your Diocese as evidenced from the gist of your reply dated 11/9/22. to a correspondent, which finds its way to the columns of our esteemed London contemporary, *West Africa* of the 7th *ultimo*.

I earnestly hope and trust your Lordship will verily pass this spirit of TRUE BROTHERHOOD on, to those of your countrymen at present in the Nigerian Service, whose Negrophobian tendency is such as to "make the Angels weep" when professing gentility to many an African in any social intercourse, otherwise, your Lordship's reply under reference, I am afraid, will be no more to others than "a sound brass, or a tinkling cymbal."

EKO AKETE

---

## ỌRỌ MẸTA TI IKUN GBỌ TI ETI RẸ FI DI!

O jẹ ede ẽbu pupọ lãrin awa enia dudu, pe nigbati a ba sọrọ fun enia ti ko ba gbọ tiwa, tabi ti a ba pe enia titi ti ko gbọ, a mã sọ pe, eleti Ikún! tabi aditi Ikún ni iwọ yi!

Kilo tilẹ jẹki eti Ikún di o? olofintoto le bẽre bẹ; gbọ o.

1. Bi Ikún ti nrin loju ọna, o ba agbọ́n, o sun kãkà, o nke pe "inụ nrun mi, inu nruw mi," Ikún ni, "ewo l' o nrun ọ nibẹ? inu oke tabi ti isalẹ?" (Sa wo ẹgbẹ agbọ́n, o ri jinginni, a ṣẽ mọ inu ti nrun u ninu mejeji?)

2. Bi o ti tun nlọ, o ba kokoro kan loju ọna, a mã jẹ "yimiyimi" o ki i tan, o ni, "nibo l' ẹ nlọ bayi?" yimiyimi dahun, o ni, "mo ngbe ẹkọ lọ si ọja lọ ta ni!!" (Gbọ? bẽni ẹlẹkọ imã doju rẹ delẹ, ti imã ṣi i? iba ṣe bẽ ni, iba ma ta pupọ!)

3. Ikún tun bẹ soju ọna, o nlọ, bẽ l' o ri ibẹnbẹdo, o nju lebelebe loju omi, o nfi idi tọ omi kẹ́rẹ́, kẹ́rẹ́, Ikún ni, "o mà ku iṣẹ o, õ ha ti ṣe omi yi, ti o nfi idi tọ́ yi?" Ibẹnbẹdo ni, "ṣa ma dakẹ, Ifa àná mi lo gba ẹja àrọ̀, mo si fẹ gbọn odo yi lati p' ẹja àrọ̀ fun àná mi!!"

(Boya o le gbọn ọsa gbẹ ki o le ri ẹja àrọ̀ pa!)

Bi Ikún ti gbọ ọrọ mẹtẹta yi tan, ni eti rẹ̀ ba di gbọnin o. Nitorina li a ṣe fi nbu enia ti a sọrọ fun ti kĩ fẹ gbọ, tabi ti a pè ti ko dahun lakoko!!

Mo juba ẹyin àgbà o.

J. M. ARIBISALA.

---

## "EKO AKETE" je Iwe-Irohin "Ilufemi."

Kosi Enia ti o polowo ọja sinu rẹ ti ko b'ode pade. Ede Yoruba ti o jina mbẹ bi Aba. Ẹ re e polowo ọja nyin sinu rẹ. Bi bẹ kọ, Afara nja ọ!

---

## OṢE!

Ni *Thursday* ọsẹ yi Adajọ kekere kọ̃ Aye (*Motion*) ti awọn Lọya awọn Adamu Animaṣawun, Ọgbẹni J. Egerton Shyngle ati Montacute Thompson, nwa lọdọ rẹ̀ lati tun gbe Ẹjọ ti a ṣe Idajọ rẹ̀ ni *Monday* ọsẹ yi, dide ni GANRAN.

## Scripture Column.

( BY M. BANKOLE FADIPE.)

*Proverbs and sayings of the Rabbis.* (*The Talmud.*)

1. Pray to God for mercy until the last shovelful of earth is cast upon thy grave.

2. The house which opens not to the poor will open to the physician.

3. Deal with those who are fortunate.

4. What is intended for thy neighbour will never be thine.

5. If the fox is King bow before him.

6. Drain not the waters of thy well while other people may desire them

7. Man sees the mote in his neighbour's eye. but knows not the beam in his own.

8. Hold no man responsible for his utterances in time of grief.

9. The foolish man knows not an insult neither does a dead man feel the cutting of a knife.

10. The thief who finds no opportunity to steal, considers himself an honest man.

11. He who is able to attend synagogue, and neglects to do so, is a bad neigbour.

12. Men should be careful lest they cause women to weep, for God counts their tears.

13. He who loves his wife as himself, and honours her more than himself, will train his children properly, he will meet, too, the fulfilment of the verse, "and thou shalt know that there is peace in thy tent and thou wilt look over thy habitation and shalt miss nothing." Job. 5.24.

14. Better to bear a false accusation in silence, than by speaking to bring the guilty to public shame.

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awon onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

Ẹ lọ de awon Ile-Ọja rẹ memeji yi : kosi-botiri ni awọn nkan to ni tun ti ta.


## LOOK HERE !!!

Send your Subsriptions for *West Africa* to me. It is cheaper to do so, saves cost of postage, time and worry.

VIDAL R. COLE,
*News Agent.*

P. O. Box 201
109 Broad Street.
Lagos, Nigeria.


## IGBẸ L' OWO WA.

### EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-ðwò wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Idapọ-Owo (A. & E. T. A.) £10 10 fun *ton* kan

| | |
|---|---|
| Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co,) | bakanna |
| Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores) | do |
| Miller | do |

### EPO.

£21 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ ọyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

### COCOA.

Lati £25 de £27 fun *ton* kan bakanna.

## ARNOLD SCHLESINGER.

### OYINBO JAMANI ONIȘOWO ARA HAMBURG

Și Ile-Owo rẹ si *No. 7*, Ita Labinjọ, I' Eko.

---

Ọgbẹni Oyinbo Jamani yi ti șe "kokari" ati fi awọn ogunlọgọ Irepe-Așọ tita rẹ han enia, ni Ile-Owo rẹ ni *No. 7*, Ita Labinjọ, ko jinna si Ita Williams, I' Eko: o si tun ni Ile-Owo ni Ita Akwaesuk, ni Ilu Calabar.

A pe gbogbo enia ti o ba fẹ ba wa ra ọja lati wa wo oniruru Ọja wa, ati awọn Irepe-Irepe Așọ l'orișiriși, tabi Iwe-Aworan Ọja wa. A ti nșowo lati igba "na-mi nna'lẹ" eyini ni l'ojọ pipẹ lati ọdun *1842*: ina owo wa si ti njo geregere ni Apa-ibi ti o jẹ Ilu Enia Dudu lati iwon ogun ọdun sẹhin titi di oni. A si ni "wabi-wọsi" awọn onibara ti Ọja wa ti dun mọ. Awa nikan I' o nta awọn MASINI IRANSO ti a npe ni "ADLER" ati eyiti a npe ni MUNDLOS (eyi ti a npe ni VICTORIA ri). A si ni MASINI ti awọn Aranbata, ti Aranșọ ati fun lilo ni 'le. A nta kẹkẹ pupupu (*Motor Bicycle*) ti a npe WANDERER pẹlu ẹrọ-ere sisa rẹ, ati eyiti a npe ni "GOLD COASTER" a si ni *Bicycle* lasan ti a npe ni "COASTER." A ni awọn Egbogi t' o jẹ bi Idan ti a npe ni BULA MATADI ati MOLOKE MONE. A si ni awọn Aworan: oniruru aworan bi ti Oluwa nigbati o wa ni Mọșalași ni Ilu Oyinbo. A si ni Duru ọlọwọ ati ti ẹlẹsẹ ti o mọ niba fun gbigbe kiri, a si ni Ẹrọ-Olorin (*Gramophone*). A si ni *Cement*, Panu Kikọle, Jigi ti Ferese ati pupọ nkan miran.

A le gba Ekurọ, *Cocoa*, tabi Epo dipo Owo-Ọja ti ẹnikẹni ba ranșẹ lọdọ wa.

Ẹ wawo, Ọja wa pọ to gbajẹ.

---

## Ẹ ȘU RIGIDI BO MI O!

OWO IRANLOWO TI A ȘI KI GBA NI WỌNYI.

| | £ | s | d. |
|---|---|---|---|
| Owo ti a ti ri gba | 9 | 1 | 6 |
| Ọgbẹni E. O. Emibius ... | 0 | 5 | 0 |
| Alufa E. A. Akinọla ... | 0 | 5 | 0 |
| Pastor A. Adedeji Isọla ... | 0 | 5 | 0 |
| Aropọ | £9 | 16 | 6 |

Ara ilu, Ẹ jare Ẹ ma jẹ ko rẹ nyin,
A o ma jihin yi lọsọsẹ,

[ED.—E. A.]

## PREACHERS FOR TO-MORROW

### AWỌN ONIWASU ỌLA.

---

**ROMAN CATHOLIC**

Masses will be sung by Priests appointed. Awọn Paddi ti a yan yi o șe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

(MORNING)

Masses Isin Arọ.

6.30—7.30 8.30—8.30
7.30—8.30 93.0—10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

**ANGLICAN**

| Time. | Preacher. |
|---|---|
| 9 a.m.—Christ Church | — |
| 6.30 p.m. | — |
| 9 a.m. & 6.30 p.m.—St. Paul's (Breadfruit) | Ven Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 9. a.m.—St. John's (Arọlọya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 9 a.m. 4 p.m.—St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m.—Holy Trinity (Ebute Ero) | Rev. S. J. Gansallo. |
| 9 a.m.—St. David's (Jordan | Rev. J. A. Leigh |

**WESLEYAN**

| | |
|---|---|
| 10.30 a.m.—Tinubu | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | Rev S. A. Pearse |
| 10.30 a.m.—Ereko | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | Rev. A. N. Cole |
| 10.30 a.m.—Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | do do |
| 10.30 a.m.—Ọbun Eko | Rev. D. A. Beckly |
| 7 p.m. | do do |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m.—Jehovah Shalom | Rev. Supt. G. A. Oke |
| 7 p.m. | Rev. I. F. Ogunko |
| 9 a.m.—Erelu | Bro. J. H. Lawson |
| 4 p.m. | do do |
| 9 a.m.—Bethel | Rev E. A. Akiọla |
| 4 p.m. | Bro. M. O. Ladẹinde |
| 6.30 p.m. | Rev. Dauphin |
| 10.30 a.m-African Methodist | Rev. N. J. D. Șomuji |
| 4.30 p.m. | Bro. A. T. Iroko |
| 9 a.m.—Ararọmi Church | Rev. A. A. Puddicombe |
| 4 p.m. | do do |

**EBENEZER**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Bro. E. A. Ojo |
| 6.30 p.m. | Rev. E C. Alabi |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO.)**

| | |
|---|---|
| 9. a.m. | Very Rev. J. G. Campbell |
| 4 p.m. | do. do. |

**BROTHERHOOD.**

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m.—Ilupesi | Bro. Fagbemi Fașeyi |
| 7 p.m. " | Pastor A. Adedeji Isọla |

**AHMADIA.**

5.30 p.m.—Open Air Service Prof. A. R. Nayyar (Vincent Street.)

**COLONIAL CHURCH (ODAN)**

A nyan Awọn Alufa si Ile Isin yi lọsọsẹ.

## THE "AJENIFUJA" SEWING MACHINES.

These Machines are German Manufactured, Constructed of the best materials and skilful workmanship, very splendid in appearance, quick action and noiseless. No confusion, simple to thread, easy to operate. Durability Guaranteed will last almost life time, call for one at Ori-Ade Store 97 & 109, Broad Street Lagos, Needles, Shuttles, etc., etc. in stock. Prices on application.

VIDAL R. COLE,
*Sole Agent.*

---

## "OṢEWỌNI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ ọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko,

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia, Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

---

### N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.

### J. F SICK ati Awọn Ẹgbẹ.

No. 7, Ita Ibode lailai, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street,*) EKO

Awọn Oyinbo onişowo yi nranṣẹ Maşini-Aranṣọ ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-Owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe Adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranṣẹ Mejila tabi ju bẹ lọ ninu Maşini na.

Awọn Oyinbo yi nṣe orişirişi Ilẹkẹ alaraoara, Nwọn si nranṣẹ (*Cement*) ati panu kikọle to nipọn, ati Ẹja Abọmafọ ati Orişirişi ọja.

Ilẹ..ue Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ Aşiri nipa Owo. Irohin ko to afojuba.

---

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

(*Macaulay's Household Dispensary.*)

A nta orişirişi ogun Ilera ni Ile-ọja yi, to wa ni popo-nla (*Broad Street,*) l' Eko ni owo pọ ọ.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun, Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Ọ. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbogi yi jẹ ẹniti o gba Aṣẹ ogun pipo (*Certificated Dispenser.*) lọwọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DAN A WO, Ogun rẹ jẹ bi idan.

## ILE OWO-ỌJA RIRANṢẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

---

Ọgbẹni S. B. Vintura, Aṣoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranṣẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Ṣẹda, Onini, Owu-Ṣẹda alarabara, Ohun-elo awọn Aranṣọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ *(Felt)* Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni tita tí owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' o kọjusi Kōtu, l' Eko.

---

## ỌGBẸNI DURO: THOMAS.

### ONIṢOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo Abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni *374*. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

---

## ILE EGBOGI IṢẸ OLODUMARE.

---

A şi ile Egbogi kan ti a npe ni Iṣẹ Olodumare si Ọja Ọbun Eko ni ile kẹta si Iga Oloye Aromirẹ. Nibẹ ni a le ri orişirişi iwosan fun oniruru aisan,

Ibaṣe fun Orififọ, Inurirun, Ẹda, Inarun, Aran Kinnişa, Ikọ, Ipa, Ọrẹrẹ, Ọṣẹ Egbogi, Egbogi Oju, ati awọn Oniruru ti a ko le to sihin tan

Rin de bẹ ki o wo o. Irohin ko to afojuba.
Iwọ ko tilẹ gbọ orukọ rẹ ndan?
Iṣẹ Olodumare !!!

Joshua O. Ade: Craig,
*Alabojuto.*

# Advertisements.

IPOLOWO ỌJA.

—:o:—


## ALASE LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWỌ."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣọwọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*:—Alawọbata, Eko.

——o——

**READY.**

**"Church and Politics."**
**(A Lecture)**

OR

THE DUTY OF THE CLERGY TO THE LAITY.
BY PROF: DENIGA.
SOLD at 24 Williams Street, Lagos.
3d. a copy.

AWON ẸGBE OYINBO ONISOWO TI A NPE NI
E. H. STEIN ARA HAMBURG.
NEUERWALL 16 18. GERMANY.

Jẹ Awọn onişowo ti Ilẹ Enia Dudu, nwọn nranşẹ Ọja fun ẹnikẹni to ba fẹ'ibaşe Ọja ti Ilu G tabi ti awọn Ilu oyinbo miran ti o wa lagbeg *England* ati Germany.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekurọ ba fi ranşẹ si wọn si Ilu awọn oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jọ enia loju.

Kosi ewu kankan ni fi fi Ọja-kọja ranşẹ si w lati Eko tabi Ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn oyinbo yi şowo tabi ki o kọwe si Aşoju wọn nibi Ọgbẹni Kari Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No. 3, tabi ni ibi- rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street.*) ati ibi-ifi Ọja pamọ si (*Forto-novo Market Store*) Eko.

Ẹnikẹni le kọwe ni ede Gẹsi, niti *German* tab niti *French*.

Oruko adugbo awọn oyinbo onişowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK. Hamburg.

GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.
MANN POOLE & COMPANY LTD.
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.
Ki la ti nṣ' oku l' ọrun?
Ki la ti nṣ' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?
Ọpọkuyọku si ni, wa şa eyi to wu ọ ni:—
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.